# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ . . .

VOL. XIV NO 819 LAGOS SATURDAY MAY 12. — MAY 18. 1962. KOBO MEJI (2D)


# Enmo Pagidari ! Ewure Bi Omo Alasopo Nilu Kano

KANO—Ni ọjọ Iṣegun (Tuesday) ti o kọja yi ni gbogbo enia lati Sabongari ati arin ilu Kano nsare ti awọn ẹlomiran nwọ mọto-ayọkẹlẹ lati lọ si ibiti nwọn npe ni Fẹgẹ lati lọ fi nkan ti o nṣe toju fun oju, ti nwọn nlọ wo ewurẹ kan ti o bi ọmọ alasopọ (siamese twins) ni agbala olowo rẹ.

Onirohin wa ti o sare lọ si ibẹ ni ọmọ merin ni ewurẹ na bi; awọn meji ti o kọkọ bi silẹ nwọn ko nṣe alasopọ rara, ṣugbọn gbogbo nwọn ni nwọn fi oju jọ ọmọ-enia.

Gbara ti olowo ẹran na, Mallam Momo Dogo, ti iṣe alapata ẹran ti ri ohun abami yi, ni o ti kigbe lọ ba awọn dokita ti nwọn nṣe itọjú awọn ẹranko, nwọn si wa fi mọto ko awọn ẹranko abami na lọ si ile ibiti nwọn yio ti yẹ nwọn wo.

Eyi ara, t'enia-t'ẹranko ni o mbi alasopọ ọmọ nilẹ Hausa? Ṣiṣọ m b ẹ lọwọ Oluwa.

## Onatade Lo Si Ilu Oyinbo

Eko—Gbogbo awọn ẹbi ati ibatan lọkunrin ati lobinrin ni nwọn pesi ebute Apapa laipẹ yi lati ṣẹyẹ-idagbere fun ọdọmọde kan ti oruko rẹ njẹ Ola Ọnatade ti o nlọ si ilu Oyinbo fun ẹkọ ijinlẹ.

Ọmọdekunrin na jẹ ẹkan ninu awọn ọmọ Owu l'Abẹokuta ti o lọ si ile iwe giga ti nwọn npe ni Methodist Boys, High School. Lẹhin eyi o ṣe iṣẹ fun-igba diẹ ni ile ifowo-pamọ kan ni ilu Eko.

A ki awọn baba ọmọ na awọn bi Ọgbẹni R. Ọnatade, Ọlalekan Ọnatade, J. L. Shodimu ati John Abati pe. nwọn ku idele, ọkọ a refo o.

## Awon Olopa Nwa Alagbeda Ti O Gba Owo Lowo Awon Ero Meka

Eko— Awọn Ọga Ọlọpanu ti da awọn enia wọn si arin ilu lati wa alagbeda kan kiri ti o gba owo-ọkọ lọwọ awọn enia marun ti nwọn fẹ lọ si Mẹka ti ko si fi o w o na jiṣẹ fun awọn Ọlọkọ ofurufu.

Onirohin wa sọ wipe alagbeda na pe ara rẹ ni aṣoju awọn Oyinbo ọlọkọ ofurufu, nipa bẹẹ Alufa Muyibi Adisa lati Igbo-ọra, san ponun mejidinlogoje fun un; Alufa Ibrahim Saimọnu lati Oke Arin, l'Eko, san iye kanna fun un. O tun gba owo bayi kanna lọwọ Alufa M. S. Asani, ni Ebute-Metta, Lemọmu Abimbọla ati Alufa Shittu Ṣodẹinde ti o ngbe Ibadan Street, l'Ebute-Metta.

Nigbati gbogbo nwọn ko ẹru wọn de idi ọkọ ofurufu ni Ikẹja tan, ti awọn ẹbi ati ọrẹ wọn ti nwọn sin nwọn lọ ṣe adura fun nwọn tan, ni awọn akọwe ọlọkọ ba tu nwọn l'ọfọ agbara pe awọn kori owo-ọkọ ti nwọn san gba, nitorina, ki nwọn pada si ile wọn.

Gbogbo owo ti alagbeda na gba lọwọ awọn enia marun na jẹ ojidin-legbẹrin din mẹrin ponun. (£756).


Advertisement No. 76.

### KERE O

OFIN TI A NFI NA OWO

ATIJỌ (WEST AFRICAN CURRENCY BOARD NOTES & COINS)

DI PI PARẸ

A fẹ la ti ran gbogbo ẹnyin enia leti wipe lati ọjọ Kini oṣu July, 1962 (Oṣu keje ọdun yi) gbogbo Owo atijọ patapata eyi ni owo Pepa ati owo Ṣile titi de ori Epini yio kunọ. Ako ni le lo wọn gege bi ofin ni ilẹ Nigeria.

Eyi ni wipe lati ọjọ Kini oṣu keje (July) ọdun yi, Owo atijọ wọnyi koni wulo fun sisan owo fun iṣẹ aje ni jake-jado ile Nigeria – fun apejuwe, akoni gba fun ọja rira tabi fun ọja tita ninu ọja ati ṣọpu.

Gbogbo ẹni ti o ba ni owo atijọ wọnyi lọwọ tabi ni ipamọ yala ni Pepa tabi ni Ṣile ni lati tara lọ ṣe pasi parọ owo wọnyi ni Bank ki Bank f u n o w o titun eyiti Central Bank ti Nigeria fi sita ni nkan bi ọdun kẹta sẹhin, ti asi ona lọwọlọyi ki ọjọ Kini oṣu keje ọdun yi (July) to to - Ọ f e ni gbogbo Bank yio parọ Owo wọnyi fun yin.

JOHN BEACH
Deputy General Manager.

Central Bank of Nigeria,
Lagos.

# AWO IRAWO

Eyi ni awọn nkan ti yio ṣẹlẹ si ọ ni ọsẹ ti o mbọ.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Ti o ba le ṣe suru pẹlu ifarada, 'gbogbo nlamọri rẹ ja bọ si dara-dara ninu ọsẹ yi.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Maṣe ronu pupọ lori wahala ibi iṣe rẹ, nitoripe wa ṣe alabapade ojulumọ tuntun, ipade na yio si ṣe ẹ ni anfani.

ARIES (Mar 21-April 20) Maṣe fi akoko ṣe're rara, gbogbo nkan ti o ba fẹ ṣe ki o tete ṣe nwọn.

AURUS (April 21-May 20) Ki o maṣe]pe nkan dudu ni funfun l'ọsẹ yi.

GEMINI (May 21-June 21) O ni lati ṣe ipinnu lori Igbesiaiye rẹ ati awọn nkan kan ti o ti nro l'ọkan.

CANCER (June 22-July 23) Ṣọra pẹlu awọn ti yio ma jowu si ọ ati nkan miran ti o le mu ipalara ba ọ.

LEO (July 24-Aug 22) Ẹnikan a wa sọdọ rẹ fun iranlọwọ, ki o maṣe roju lati ṣe iranlọwọ na fun-un.

VIRGO (Aug23-Sept 23) Gbe ogun ti irẹwẹsi ti o nṣe ọ, ki o si g'a ara rẹ lọwọ rẹ.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Ko si ọna wipe ki o mọ ṣe olulaja fun awọn ẹnia kan ninu ọsẹ yi.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Nkan ti o ko ro tẹlẹ a dari rẹ si ọna miran, a si je ki onipese je ọ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Iṣẹ tuntun tabi ero nkan rere ti o ba da labẹ a yọri si rere.

APRICORN (Dec 23-Jan 21) Iwọ alara paapa nfẹ atunṣe ara rẹ, ki o si ro bi aiye rẹ ti nlọ si.

# Erin Gb'ojikan Ninu Ile Igbimo Ilu Ghana

ACCRA — Ẹrin nla ni o bẹ silẹ ninu Ile Igbimọ Aṣofin ilu Ghana nigbati ọrọ de ibiti nwọn ngbe sọrọ ibisun Wura, (Gold Bed) ti iyawo Ọgbẹni Krobo Edusie ra nilu Oyinbo.

Nigbati nwọn nṣe ariyanjiyan lori ile tubu, (Ọgba ẹwọn) ti ilu Ghana, ti Ọgbẹni Edusie sọ wipe ẹlẹwọn ti isisiyi gbadun pupọ ju ti atẹhinwa lọ, nkan bi ọdun mẹwa s'ẹhin ti on paapa lọ ṣe ẹwọn nitori ọrọ iṣelu.

O sọ wipe ori ẹni koriko ti o gun to ẹsẹ mẹta ni ẹlẹwọn fi nsun, ṣugbọn nisisiyi, awọn ẹlẹwọn nsun lori ibusun. (Bed). Nibẹ ni ẹnikan ninu awọn ijọ Alatako ti ja nikoro wipe, "nwọn nsun lori ibusun"?

Gbogbo ile bu s'ẹrin, pelu ẹrin na ni Alaṣẹ Ile Igbimọ fi sọ fun Ọgbẹni Edusie wipe, ki o ma ṣe dahun si ibere na nitoripe ko tọ suna. Ọgbẹni Edusie si mba ọrọ rẹ lọ, o sọ pe awọn ẹlẹwọn ti ode oni nsun lori ibusun onirin.


## Awọn òwò ṣiṣe tuntun ni ijeri si ilọsiwaju




Adọrin ọmọ Nigeria lowa ti wọn da duro fun rawọn bi oniṣowo keke Raleigh.
UAC nṣe iranwọ fun idasile ile-ọṣẹ ti irin-iṣẹ wa pupọ si lati ko wọn ni ẹkọ iṣẹ.

# UAC

# nran awọn ọmọ Nigeria lọwọ lati di onisowo asiko ati lati da duro fun rawọn

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED


# Okunrin Kan Gun Eniti O Pee L'ejo Lobe

Abakaliki—Ni aipẹ yi ni ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Gabriel Akamereigwe, ẹni ọdun mọkandinlọgbọn ti iṣe iṣẹ kapinnta ni abule Idoko lẹba Abakaliki pade agbako, ti ẹniti on alara pe lẹjọ si kotu gun ni lọbẹ pa patapata.

Ọrọ na lọ bayi, Akamereigwe, on ati aladugbo rẹ kan ti o njẹ Otwzu Nwofoke, ni gbolohun-asọ lori oko ti nwọn ngbin irẹ-i si kan. Otwzu ni t'on ni ilẹ na, Akamereigwe paapa ni t'on ni. Ọrọ na fẹ b'Ige b'Adubi ni Akamereigwe ba lọ pe aladugbo rẹ na lẹjọ si Kotu.

Lọjọ ti akọwe kotu, Nwankwo Onyia, fẹ muiwe-pẹjọ na fun ọdanran yi ni ọdaran na yọ ada si nwọn, ti o bẹrẹsi ṣa ẹlẹjọ rẹ ni aṣapa. Wara-were akọwe Kotu ti fi ẹsẹ fẹ.

# Gomina Titun Ati Alase Pataki Ilu Malta



Ọlọla Sir Maurice ati Omidan Dorman, ti iṣe iyawo Ọlọla Maurice Dorman ti Ọba Alaiyeluwa ṣeṣe yan lati jẹ Gomina Titun ati Alaṣẹ pataki ilu Malta ni a nwo ninu aworan yi.

Niba ṣoki, Ọlala Sir Maurice gba oye C.M.G. ni 1955, K.C.M.G. ni 1957 ati oye nla G.C.M.G. ni 1961. On ati Omidan Dorman iyawo rẹ, bi ọmọkunrin kan ati awọn ọmọbinrin mẹta.

# R'ERIN PELU ELETI-OFE KI INU RE DUN

ỌSITẸRITI MẸṢỌ

(Lati ọwọ J. Ọla. Wins)

Okunrin kan sọ fun iyawo rẹ wipe o to akoko ti ao ma ṣọ owo na, ọsitẹriti mẹṣọ ti de, owo onjẹ wa yio dinku pupọ. Iyawo ni bale mi kini o njẹ ọsitẹriti mẹṣọ? Ọkunrin na ni ki a ma fi iṣiro si owo ti a nna, owo ọbẹ yio dinku, paapa owo onjẹ wa yio din ponun mẹrin losoṣu. Iyawo ni ah! ohun ti o njẹ ọsitẹriti mẹṣọ ni yẹn!

Ki ọkọ to lọ si ibi iṣẹ, o sọ fun iyawo rẹ ki o toju onjẹ adidun silẹ ki on to de; kete ti ọkọ lọ ibi iṣẹ ni obinrin yi ba tọju awo funfun ti o mọ dada mẹta silẹ, o fi gari sinu ọkan, ofi nmi tutu sinu ọkan, o wa fi ẹpa sinu ọkan to ku; o gbe gbogbo rẹ ka ori tabili onjẹ.

Bi ọkọ ti ti ibi iṣẹ de, o kan bọ sori aga, yio jẹun, bi o ti si awo kini, o ba gari oloyọ, o si awo keji, o ba omi ninu rẹ, o si awo kẹta, o ba ẹpa gbẹwuru ninu rẹ, o fi ariwo ta, o ni ha! ha!! iyawo, ki ni eyi? Iyawo ni ọsitẹriti mẹṣọ ni kẹ!

X X X

Olukọ kan sọ fun awọn ọmọ ile-ẹkọ rẹ wipe lati bi ọjọ mẹta ni on ti j'iṣu. Ọmọ ile-ẹkọ kan sọ wipe, tisa, a ṣe ẹnyin ni ẹ nko iṣu baba mi, ole ni ọ sa!

Olukọ na wipe, ha! emi ki iṣe ol o, nkan ti mo wi ni pe, mo nji nya'gbẹ ni o.

## Ariya Odun Ketala Oku Iya Ibiteye Pa-bambari

Ogidi Ijimun— Ọgbẹni P. S. Ibitẹyẹ ati awọn aburo rẹ ṣe ariya ọdun kẹtala oku iya wọn ni ilu Ogidi niwọn ibuso mẹjọ si ilu Kabba, aiye gbọ ọrun mọ ni a le pe inawo ọjọ na, nitoripe, bi ilu Ogidi ti to, bẹni awọn enia alabaṣẹyẹ fi pọ to, awọn ọmọ oloku si fi ile pọn'ti, nwọn fi ọna ro'ka, jijẹ ati ohun mimu ni nwọn fi tẹ gbogbo enia lọrun.

(Wo yoku lofu ewe kefa)


# OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

# E Polowo Oja Nyin

## Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe




E Ma Se Fomi Sofo mo

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosọkọ Street. Lagos, "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 819. SATVRDAY MAY 12- MAY 18, 1962


# Ojo Ose Ola Ni Ojo Na

## Ranti, Magbagbe

A fi wosika wa ọsẹ yi kesi ẹnyin ọkawe wa ati gbogbo ẹnyin enia wa jake-jado ilẹ Nigeria, lati ṣe nyin ni iranti wipe ki a maṣe gbagbe ọrọ ti enia ti Ijọba wa nfẹ lati ka fun ire ati ilọsiwaju orilẹ-ede wa.

Gẹgẹ bi a ti nkede rẹ, ti awọn Iwe Irohin nkede ṣe alaye nipa kika awa enia ilẹ Nigeria, bẹna ni awọn Ile iṣẹ Ẹrọ Asọrọ-ma-gbesi nke tantan pẹlu alaye kikun si etigbọ ẹnikẹni wipe ko si nkan iṣeyemeji ninu enia kika, ko ni ọrọ owo ori tabi owo-ode sisan ninu ayafi anfani ainiye fun awọn ilu wa, gẹgẹbi ipese Ile Iwosan, Ile Ẹkọ iwe, eto awọn aṣoju ti o ba tọ lati ṣ'oju ninu Ile Igbimọ Aṣofin ati Igbimọ ibilẹ pẹlu awọn nkan won-ni fun afani awọn enia ilu kọkan gẹgẹbi nwọn ba ti pọ to.

Nitorina, ẹ maṣe kọ lati yọnda ara yin fun awọn Onişẹ akaria pẹlu iranlọwọ, ki a ma baa ke abamọ.

# Jamba Moto P'apoju Ni Ona Ikorodu

THE FAULTY DRIVER




Lati bi ojo meta wa ni irohin ti nkan wa wipe ojojumo ni jamba moto nsele ni ona Ikorodu mo Shomolu. Agbako moto nwonyi po tobe gee ti awon kan ti nwon kolu ara won jona pata-pata pelu awon ero inu won. Iru awon awa-moto oniwakuwa ti e nwo aworan re ni apakan iwe yi ni o nfa sababi jamba awon moto na.

# Iwe Si Olotu

## Ojo Idi Bosi

Ẹ jọwọ, ẹ gba mi ni aye ninu iwe irohin nyin lati kesi awọn Munisifa onişẹ bọsi wa l'Eko, ki nwọn jọwọ ki nwọn ba wa kọ ile - iduro bọsi (sheltered bus stop) ti o ni ile lori kakiri ilu Eko, Apapa, Ebute Mẹtta ati Mushin titi de Oshodi nitoripe akoko ojo ni a wa nisisiyi.

Ẹnikẹni ti o ba ri ojo ti o rọ ni owurọ kutu-kutu ọjọ Wednesday ti o kọja yi bi o ti pa gbogbo awọn ero ti o duro si idi bọsi na ni ipakupa oluwa rẹ a wipe nitotọ ni o yẹ lati kọ ile iduro bọsi ti o ni ile lori.

Ni ilu Aganyin ni Ghana, gbogbo ile iduro bọsi wọn ni o ni ile lori, bi ojo ba nrọ tabi orun nran wa ri ibi sa si.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa kesi awọn Munisifa onişẹ bọsi na ki nwọn gba wa o.

Emi ni,

EKO S. Akamọ

## Jamba Moto Yi Po

Ẹ jọwọ ẹ ba wa bi awọn Olotu Ijọba wa wipe kiloṣe ti nwọn ko le ri nkankan ṣe si ọrọ jamba moto ti o npọ si lojojumọ ni ilu Nigeria.

Ni ọkan temi, o dabi ẹnipe awọn Ọlọpa a-mu-mọto (traffic police) wa papa ni o ngba awọn awa-mọto na laye. Bi nwọn ba ko ero ju iye iwe-aṣẹ wọn lọ, awọn ọlọpa yi a f'oju fo o da; bi nwọn ba si nsare bi ọkọ ofurufu, nwọn a maa wo nwọn.

Ọpọlọpọ awọn awa-mọto wa na bi nwọn ko ba iti mu ọti amupara, ki nwọn bẹ taba "igbo" si ori, nwọn ko ni wa-mọto wọn na ni awapa.

Ofin ti o da sẹriya nla fun awọn ti o ba wa-mọto ti nwọn ba ti mu ọti ki nwọn jọwọ ki nwọn lo fun nwọn, ki nwọn ye pa awọn ẹni-ẹleni lojojumọ.

Emi ni,

Ijẹbu-ode S. Salakọ

# Nihin, Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

ẸNYIN MUSULUMI, Ẹ KU ỌDUN!

Mo ri wipe o yẹ ki nki gbogbo ẹnyin Musulumi ti o nkawe mi wipe, ẹ ku ọdun Ileya, ẹ si ku iyedun. Ni ọdun ti o mbọ gbogbo wa ni a ri owo fi ra agbo mẹta mẹta, nitoripe "MẸ" ni iyawo ti Ọlọrun pa laṣẹ fun awa ọkunrin ti a ba jẹ Musulumi ngko wipe awa Imale o.

Boya ẹ ko mọ wipe Imale wa jara ninu wa, bẹsini awọn Musulumi ? Iwa awa Imale a le kokoko, iwa Musulumi a si rẹwẹsi nitoripe awọn ko fi irun - kiki ṣ'ere, bẹsini wa ba Alukurani wọn lọwọ wọn nigbakugba.

Bi nwọn ko ba gba awẹ, nwọn a ṣe saara lọjọ Ẹti (ti nwọn npe ni Jimọ) nitoripe saara ni ẹbọ Musulumi. Sugbọn sibẹsibẹ alejo ni gbogbo wa ni ilu Mẹka. Emi Ayiluka ko gbọdọ jarọ, sugbọn gbogbo wa ni a mọ wipe lehin ọjọ meje ede "Ka Suru Beka La Barika" ni, nwọn a ma sọ fun nyin.

Itumọ ọrọ na ni wipe, "Ẹ wa o, ṣe esin ni ẹ sọ wipe ẹ wa ba wa se? Ẹ tete ma a lọ si ilu nyin gbogbo ẹnyin enia yi"

O to asiko fun awa na nisisiyi, o si yẹ ki a ma gba awọn Musulumi agbaiye ni alejo ni Nigeria. Oke Olọjọ wa ni Ile Ifẹ; oke Lekeleke wa ni Sokoto; oke Iṣoro wa ni Ẹnugu; oke Olumọ wa ni Abẹokuta. Kosi eyiti a pa agbo ẹran Ileya lori re ti Olodumare tabi Allah wipe On ko gba. Oke ni oke jẹ o.

GBOGBO IJAIYE KU AJAIYE

Ṣe laipẹ yi ni mo sọ fun ẹnyin ti o nka'we mi wipe mo fẹ lọ si ibi ifinijoye kan ni Agọ Ijaiye l'Abẹokuta? Ṣugbọn nisisiyi a ko pe Agọ Ijaiye ni Agọ mọ. Alejo ti o ba ti ṣe ọgọrun ọdun tabi ju bẹ lọ nibikan ti kuro ni alejo, o ti di ọmọ onile.

Ọmọluwabi ki i fi ọwọ osi juwe ile baba rẹ; ile baba nikan kọ, ile iya paapa pẹlu. Ni Orile Ijaiye ni nwọn ti gbe bi iya-iya mi ati baba-iyami pẹlu. Nwọn loyun emi paapa ni Owu, nwọn bi mi si Ijaiye-iya baba mi, Bọlajoko, wa sọ mi ni Ọlalekan Ijaiyegbemi.

Kinni o wa ṣe ti nko fi ni mọ itan Ijaiye bi ẹni mọ owo? Gbogbo ẹnyin ọmọ Ijaiye ẹ ku ajaiye, ẹ ku ori rere ti oye ti nwọn fi Ọgbeni wa, Ilọri, jẹ laipẹ yi.

Mo ki gbogbo awọn Ẹgbẹ ọmọ Ijaiye ni Ibadan, ni Orile Ijaiye ati l'Eko; mo ki awọn bi Oloye wa, Oluokun Lawale, A. Fashọla, J. K. Ajala, Salawu Adediran (Ọpẹloyeru), Alhaji K. Adelabu, Yesufu Adeshina (Olori), S. Ọla, Bada, Gbadamọsi Arẹ, Badiru, Alhaji Ajifẹrukẹ, Bọlaji Abiọse, Adeṣọkan, Akande, Fagbemi, Iya'fin Creppy, 'Doyin Ayọrinde ati Shitta.

Oye na a mọ'ri o.

IJAYE LO NI OKE ARIN

Gẹgẹbi mo ti ki ẹnyin ọmọ Ijaiye wipe ẹ ku otire ti o yẹ nla ti nwọn fi da nyin lọla ni Abẹokuta, mo si tun ni lati ki nyin ku ọfọ meji ti o ṣe lera wọn ninu oṣu yi.

Ikinni ni, ti ọdọmọkunrin kan ti nwọn npe ni Lasisi Layẹmi, ti o jalaisi ni Ọlọrunṣogo, Mushin, laipẹ yi. O jẹ gbajumọ Olorin nigba aiye rẹ. Gbogbo enia ni ilu Eko ni nwọn maa nwa si Oke Arin lati gbọ orin rẹ.

Ijaiye ọmọ Layẹmi, "tani f'ada k'ọla fun ẹdiẹ" ? O di arinna ko!

Ẹnikeji ni Iyafin Letty Joseph. Iyawo Ologbe Ben Joseph. Arẹwa Obinrin yi ni ẹnikini ninu awọn Obinrin Nigeria ti o kọ wa-moto ayọkẹlẹ ni igboro Eko. Ọmọba ni ni Ilesha, ṣugbọn iyawo ọmọ Ijaiye ni.

Nigba aiye rẹ ti o ba nję iyakọ, ti o si nki ọ ni oriki mẹsan, mẹwa, wa ṣebi o ṣẹṣẹ ti Orile Ijaiye de ni.

Ọmọ Owa, bi o ba de ọrun ki o o ṣe orun re o; maṣe sun gbagbe Tunde, Femi, Fọlarin ati Bọla aya Glover.

ỌMỌDE MẸṢỌ, Ẹ KU !

Mo ki ẹnyin ọmọ ẹgbẹ ti nwọn npe ni ọmọde Mẹṣọ l'Eko wipe ẹ ku ọfọ ọkan ninu nyin ti o jalaisi ni aipẹ yi, ẹ si ku ọdun ; ṣugbọn ọrọ aṣiri kan ni mo fẹ tẹ mọ gbogbo nyin leti. Ọrọ na ni wipe gbogbo nyin ti kuro ni ọmọde, ẹ gbajumọ, ẹ si ni owo lọwọ, ẹ kọle, ẹ kọ aṣẹ, orukọ ti o yẹ nyin nisisiyi ni AGBA MẸTỌ, kini o wa nṣe n yin ti ẹ ko le ma ṣe waasi ati wasu fun awọn wundia iṣẹ; nyin Pẹ .....ọrọ pọ nibẹ. Tabi ẹ fẹ ki nla ọrọ na mọlẹ ni ?

Ọrọ apara nla bi : Fi ina si i, mo ni ki o fi ina si; asiko rẹ ni o ẹ bẹrẹ mọ'lẹ ki ẹ mu nambа, ki ẹ ṣe ẹ gbajumọ, ki ẹ mu iyawo lọ; ki ẹ da'mi silẹ, ki ẹ tẹlẹ iutu "tabi bẹbẹ ko tilẹ yẹ ita nyin mọ.

ẸGBẸ KILỌKỌ-O-ṢE

Emi paapa niran igbati mo mba awọn ọmọ ẹgbẹ gbajumọ kan : a npe ni Ẹgbẹ KILỌKỌ-O-ṢE nia ni ilu Ibadan. Nnotọ ko si ọkọ ẹnikan ti o ti ṣe nkankan fun wọn, ṣugbọn nisisiyi akoko nkọ olukaluku. Gbogbo ọrọ na wa di ọrọ ẹsẹ ya ju moto lọ; ọrẹ mi, ara ni o nfi abọ si.

Lẹrinkan si, mo ki nyin, ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun, ki ẹ fi ẹran agbo temi silẹ fun mi, ṣugbọn ọti jinni nii' ọti kọ'ja ni mo fi nlo'gun. Bi ẹ ba si wa ki emi na ma fun nyin ni ọti wiski ti ẹ ko ba ni ewọ rẹ nitoripe mo gbọ wipe Alufa kan tisẹ ni Ikilọ fun nyin.

O digba o.

# Ere Bolu Afesegba



Ẹ wo aworan awọn elere bọlu afẹsẹgba, Terry Medwin, bi o ti fo soke gba bọlu ni agbawọle, ti Aṣọle bọlu (Goalkeeper) Bobby Jones fi ọmọ ika-ọwọ ta danu, ninu ere bọlu afẹsẹgba ti nwọn ṣe ni ilu nla London.

## Elewon Kan Pa Ara Re Si Ijoba Lorun

Eko— Idamu nla ni o ba gbogbo awọn ẹlẹwọn ninu ọgba wọn l'Eko ni ọsẹ ti o kọja yi, nigbati nwọn ri ọkan ninu nwọn ti o njẹ James Adelẹye, ninu agbara ẹjẹ ti o nlọgun too, ti o nkigbe pẹlu irora lẹhinti o ti fi abẹ kan ge ara rẹ lọna ọfun ti o si fi ku pa apata-

Irohin ti a gbọ nipa ọrọ ẹlẹwọn na nipe, o ti da'ran kan ti nwọn fi sọ sẹwọn ọdun gbere (life imprismm-ent); in ọrọ yi ni o nro, ni o ba fi mu ọbẹ alafẹfẹ ti nwọn fi nfa irun agbọn, ti o fi ge ara ni ọna-ọfun.

## Ariya Odun Ketala Oku iya Ibiteye Pa-bambari

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Awọn enia nla-nla ati awọn enia pataki-pataki ti nwọn fi ọla wọn bukun aṣeye oku iya onisurere na ni, Ọba ilu Ogidi, Kabiyesi, o Minisita S. A. Ajayi, awọn Oloye Ọbagunle, Elẹga, Elela, Onirun lati Eriti, Olukun, Alafo Ọba Olukare, Elekiya, Ọlọwọ, Eletigo, Oludoyi ati Onisẹ Olokoro ilu Okoro.

Ẹni-ọwọ Alufa D.O Oladugba l'o fi adura si ariya aṣeye na ni agogo mẹsan owurọ, pẹlu awọn Ọgbẹni T. Olupẹka, Baba ẹgbẹ C.M.S. Medupin Baba ẹgbẹ R.C.M.

(Wlo yoku loju ewe keje)




# Adajo So Omo Egbe Olomi Kan Sewon Ni Ilorin

Ilọrin— Laipẹ yi ni adajọ kotu nla kan ju ọdaran kan ti orukọ rẹ njẹ Raji Balogun, ẹni ọdun meji-dinlọgbọn tiṣe ọmọ ẹgbẹ Olomi (N. P. C.) si ẹwọn oṣu mejila nitoripe o ba mọto ayọkẹlẹ Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin, ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ jẹ.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ba ọdaran na ro ni wipe, ninu ọdun ti o koja, on ati awọn Alihaji Sanni Balogun ati George Ademọla Ogunniyi lu Ọlawọyin nwọn si ba mọto ayọkẹlẹ ti o wọ jẹ, nwọn ni nitoripe o fi mọtọ rẹ na pa ewurẹ kan ni oju'de awọn ni Ọffa.

Nigbati Raji ro ẹjọ tirẹ ,o ni irọ ni nwọn pa mọ on, o ni on ko fi ọwọ kan Ọlawọyin rara, o ni ṣugbọn nitotọ ni awọn da mọto ti o wọ na duro nigbati mọto na kọlu ẹran awọn.

Nigba'i nwọn ro ẹjọ na siwaju, ti nwọu ro s'ẹhin, adajọ ni o jẹbi, o ni ti ọdaran na ba jade lọgba ẹwọn ko gbọdọ ṣe ijangbọn fun ọdun meji gbako.

## Oba Akure Fe Lo Si Ilu Oyinbo

AKURẸ – Gbogbo ọmọ Akurẹ lọkunrin lobinrin nmura lati ṣe aṣeyẹ pataki fun Ọba wọn, Alaiyeluwa Ademuwagun Adeṣida Keji pẹlu Olori rẹ, Eyesorun, ti nwọn npalẹmọ lati lọ si Oyinbo ni aipẹ yi.

Gẹgẹbi ẹto ti awọn Oyinbo ti o fẹ gba wọn ni alejo ni ilu Oyinbo na ṣe silẹ fun wọn, a gbọ wipe Alaiyeluwa na ati Olori rẹ a wọ'kọ elefin ti nwọn npe ni Aureol ni Apapa l'Eko ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi, nwọn a ṣe ọjọ mẹdogun ninu ọkọ na ki nwọn to gunlẹ si ebute Liverpool.

Gbara ti nwọn ba ti gunlẹ ni awọn Oyinbo ti o fẹ gba wọn ni alejo na a ti bẹrẹ aṣeyẹ ti wọn ti nwọn ti mura silẹ fun nwọn.

Onirohin wa ni on gbọ wipe gbogbo ibi pataki-pataki ni nwọn a mu lọ ni ilu Oyinbo na.

Ọkọ a refo o!

**Ema Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe**

Ti o kun fun Irohin Aladun L'osose

**ELETI-OFE D'ARABA**

## Two Nigerian Accountants Meet At Work In London

LONDON—A twelve-year chain of coincidence in the lives of two Nigerian accountants will come to an end (temporarily at least) when Mr. Abubakar Omo-Ikoroda, of Ibich Ugiekha Afenmai division, Western Region, returns home from Britain in July this year.

Since they joined the Federal Civil Service more than twelve years ago, Mr. Omo-Ikoroda and his friend Mr. Adebayo Adesanmi, of 34, Akui Street, Ile-Ife, have seldom been apart for more than a few days at a time. They began work in the same office. Together they survived several transfers without ever being separated. And the most remarkable event in the chain of coincidence that seemed to link their lives came when they arrived in Britain on Federal government scholarships within a day of each other.

At Leeds College of Commerce, where they studied accountancy together, they both passed the Association of Certified and Corporate Accountants' examination in two years-normally the course takes three years. After that they were both accepted by the same big Leeds industrial firm employing over 4,000 workers, for work in the cost accounting department where they are gaining valuable practical experience.

But in July the partnership breaks up; when Mr. Omo - Ikoroda returns to government service in Nigeria. Not for long however, Mr. Adesanmi too returns home later in December - he is waiting until his wife has completed her studies at Leeds College of Commerce.

### LONDON COURSE ON HOSPITAL ADMINISTRATION FOR NIGERIANS

London-Three Nigerians are among twelve senior officials from eight countries who yesterday started a twelve weeks course on hospital management in London. They are Mr. David Oluwadare Ola and Mr. Ezikiel Ojo Oyedeji, both of the Federal Ministry of Health, Lagos, and Mr. Matthew Fyneface Sibi of the Eastern Ministry of Health, Enugu.

Under the Special Commonwealth African Assistance Plan, they will join the course arranged by Britain's Department of Technical Co-operation in conjunction with the King Edward's Hospital Fund for London.

The second of its type organised by the fund, the course offers to students a general background of the origin, introduction and development of the National Health Service in Britain, together with detailed practical experience of the organisation and work of the Ministry of Health and hospital boards, committees and related authorities.

The Nigerians will join hospital administrators from India, Malaya, the Philippines, Aden, British Guiana, Borneo and Uganda.

### THREE NIGERIAN PARLIAMENTARIANS AT BRITISH RECEPTION

London—Three Nigerian Parliamentarians were the guests of Mr. Duncan Sandys, Secretary of State for Commonwealth Relations, and Mr. Reginald Maudling, Colonial Secretary, at a reception organised by the General Council and British branch of the Commonwealth Parliamentary Association at Lancaster House in London on Monday evening.

They were Chief J. A. O. Odebiyi, Minister of Finance and Leader of the Western House of Assembly, Prince the Hon. A. Adedoyin, Speaker of the Western House of Assembly and Mallam Muhammadu Sokoto, Parliamentary Secretary to the Northern Ministery of Justice.

They were among representatives from twenty-three overseas legislatures now in London to atte and the eleventh course in Parliamentary procedure and practice at Westminister.

# British Railways First Women Electrical Engineer



GLENY Walley, who recently joined British Railways as an electrical engineer, testing signalling equipment on the main Manchester-London line near Coventry, England.

23-year-old Gleny is believed to be the first woman to hold the job of electrical engineer with the railways.

## Ariya Odun Ketala Oku Iya Ibiteye Pa Bambari

(O bere loju ewe kefa)

awọn Ogbẹni S.M. Fadile ati iyawo rẹ, R.O. Dare, Antoni Alatẹgun, Matiu Olukarẹ lati Ikarẹ.

Ki a da diẹ ninu orukọ awọn obinrin to peju - pesẹ sibi aṣeyẹ na : Iyafin E.A. Ajọkẹ Ibiteye, Ariyeke Ibiteye, Abigeli Ibirawo, Barikisu, S. Meroh, E. Bobinin, Oladugba, Iyalode, J. Wuraọla, Adepọju Abiọla, Sifawu Otẹtubi, Alade pe Dawudu.

Aki awọn ọmọ Oloku na ku inawo, ẹhin iya na yio dara, ọmọ ni yio ṣ'ẹhin fun ẹnyin na o. Awọn ọmọ Oloku na ni : Ogbẹni P.S. 1,Ibiteye, 2, S.A. Abiọla, J.S. Otetubi, 4 Iyafin D. Fọlakẹ Ajayi, 5 Ọgbẹni J.A. Dawodu Amuda.

# Alase Awon Ilu Okere Titun Nile Igbimo



Aworan ti a nwo ninu iwe yi niti Olọla Lord Lansdown ọmọ ọdun mọkan-din-ladọta, ti nwọn sẹṣẹ yan si ipo Alaṣẹ awọn ilu Okere titun dipo Olọla Lord Perth, ti o fi aye na silẹ.

## Awon Ara Meka Ko Ebun Awon Larubawa

Jẹda—Irohin ti onirohin wa fi ranṣẹ si wa ni pe gbogbo ogunlọgọ awọn enia ti o ṣe Haji ni nwọn ti gunlẹ pata-pata si arin ilu na nisisiyi a fi ọkọ elefin ti o nkọ ẹgbẹ-run ara Misira lọ si Mẹka pẹlu ẹbun nla ti awọn Larub-awa maa nfi ta ara ilu Mẹka lọrẹ lọdọdun ti nwọn ni awọn ko fẹ, ki nwọn majẹ ki o gunlẹ.

Irohin na lọ bayi : ni ọdọdun ni awọn Larubawa (Arab) nma ta awọn ara Mẹka lọrẹ aṣọ nla (silk Carpet) ti nwọn maa nlo lati fi bo okuta Kaba ti gbogbo awọn Alhaji nma alọ kirun si lara.

Awọn ara Mẹka ni awọn ko fẹ, nitoripe ti ọdun tokọja ti nwọn fun awọn Ko dara rara, ki nwọn tun gbe nkan wọn lọ; awọn ero Mẹka ti o wa ninu ọkọ na paapa bafiada kọri wipe awọn na ko ni bọsilẹ ninu ọkọ.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23379; Olola L. A. OJO, 12 Inabere Street, Lagos.

## Alaye Egbe Omo Ilorin Ti Nigeria Fun Ibere Amoda

Gẹgẹ bi Ibere Y. Amọda ni ijọ 28 oṣu April 1962 O dun ninu mi pupọ lati fihan Onibere na pe awa ni ọpọlọpọ anfani ti a nṣe pelu ẹnikẹni to ba jẹ ikan ninu gbẹ yi nigbati iṣoro ba de baa.

Akọkọ fun ẹniti odi arugbo, ti ko si ni enia, ao gbe pada sile ki o ma di oku Eko.

Ikeji ni wipe, enito ba ku, o ni enia ni, ko ni enia ni awa yio pa aṣiri rẹ mọ.

Iketa nipe, awa si nṣe eto lọwọ-lọwọ nisisiyi lati da iṣẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ilọrin, tabi ẹniti o wa ni agbegbe Ilọrin, tabi ẹnikẹni to ba wa ni abẹ Ọba wa ni Ilọrin, ki wọn mafi le mọ nkan ti wọn npe ni iya, eyi todaju pe pupọ ọmọ Ilu miran fi nṣe anfani silu wọn, nipa bayi, eyi ti awa na gbedani nisisiyi ni wipe, ki awa na le ri ilọsiwaju ilu wa.

Lẹhin eyi, ninu iṣẹ wa, ti a gbe dani ni pe, ki iwọ Onibere le mọ amọdaju, bere nipa Alfa Tukuru Adio to ngbe No. 17, Jinodu Street, Mushin, nigbato ku si Ile Iwosan (General Hospital Lagos) iru iṣẹ ti awa ọmọ ẹgbẹ Ilọrin ṣe ki a to ri oku rẹ gba, ki o si bere gẹgẹbi a ti ṣe pa aṣiri rẹ mọ.

Nidi bayi, awa jẹ ẹgbẹ to nbo aṣiri ara wa ati ti ẹlomiran, fun ilọsiwaju ibere rẹ, tun wo iwe ọsẹ to mbọ, iwọ na yio tun ri alaye siwaju si.

Alhadji A.W. I. Anifowoṣe,
Akọwe Ẹgbẹ na.

## Obinrin Ti O Ko Wa Moto-Ayokele Jalaisi

EKO — Anu ṣe awa Onirohin "Eleti - Ofe" Tati tufọ Ọmọba Iyafin Letty Joseph, aya Ologbe Ben Joseph fun nyin. Iya yi ni obinrin kinni ni ile Nigeria ti o kọ kọ bi a ti wa ọkọ mọto ayọkẹlẹ (motor car) ni ile yi ti o wa mọto na ni igboro Eko.

Ọmọ Ọba (Hastrupp) Ọwa Ilesha ni iṣe ni ilu rẹ, ki ọkọ rẹ, Ben Joseph, ọmọ Ijaiye to gbe ni arede ni nigbati iyi wa lara awọn alarede ni Eko.

O ko leri ọkan ninu awọn ẹbi rẹ tabi tọkọ rẹ ti a wipe o ṣe on nigbakan ri, bẹsini ni adugbo ti o ngbe ati ni Ile isin (Ṣọọṣi) ti o nlọ.

A ki gbogbo awọn ọmọ'loku ati ẹbi ologbe na, nwọn ku aṣẹhinde.

## Ranti, Magbagbe ! Ojo Ose Ola Ni Ojo Ikania, Jeki Nwon Ka o.

E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe